# NI ỌNA EMMAUSI

## Luku 24:1-48

### ẸKỌ 65 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "O jinde ni ijọ kẹta gẹgẹ bi iwe-mimọ́ ti wi" (1 Kọrinti 15:4).**

**Iboji ti o Ṣofo**

Kristi ti ṣẹgun gbogbo awọn ọta Rẹ̀, iboji kò le di Ọmọ Ọlọrun mú. O ti wi tẹlẹ pe Oun yoo jinde ni ọjọ kẹta; nigba ti ilẹ ọjọ naa si mọ́, ko si agbara eniyan kan -- okuta ti a yí di iboji, edidi ijọba Romu, awọn ọmọ-ogun ti n ṣọ́ iboji naa – ti o le di Olugbala ti O jinde mu. O ti san owo irapada wa. O si ti gba iye-ainipẹkun fun wa.

Awọn ọmọ-ẹyin kò gba awọn obinrin ti o wi pe awọn ti ri iboji pe o ṣofo gbọ́, ati pe awọn ti ri awọn angẹli ti o sọ fun wọn pe Kristi ti jinde. O dabi ẹni pe wọn ti gbagbe gbogbo ohun wọnni ti Jesu ti sọ fun wọn nipa ajinde Rẹ̀. Wọn ti gbagbọ́ pe Jesu yoo gbà wọn lọwọ ijọba Romu; ṣugbọn nisisiyii O ti kú, inu wọn bajẹ to bẹẹ ti wọn ko tilẹ ronu nipa ajinde Rẹ̀.

Awọn akọwe ati awọn Farisi ko gba Jesu gbọ́, ṣugbọn wọn ti gbọ pe o ni Oun o jinde ni ọjọ kẹta, wọn si ranti. Wọn ri si i pe a fi edidi di iboji naa daradara ki ẹnikẹni ma baa wa ji oku Rẹ̀ gbe lọ ki wọn si maa wi pe O ti jinde. Ṣugbọn awọn ọmọ-ẹyin ti gbagbe. Nigba tiwọn tilẹ ba iboji ti o ṣofo wọn ko mọ ohun ti o ṣẹlẹ.

**Lọra lati Gbagbọ́**

Nigba ti meji ninu awọn ọmọ-ẹyin Jesu n lọ si Emmausi ni alẹ ọjọ ọsẹ ni, wọn ro pe ireti wọn ikẹyin ti pin. "Alejo" kan dé saarin wọn o si n fẹ mọ ohun ti o fa a ti wọn fi kún fun ibanujẹ bẹẹ. O yà wọn lẹnu pe ko mọ nipa ohun ti o ṣẹlẹ ti o mu ki gbogbo ilu Jerusalẹmu wa ninu rogbodiyan bẹẹ, wọn si sọ fun Un nipa idajọ aitọ ti a ṣe fun Jesu ati kikan ailaanu ti a kan An mọ Agbelebu. Alejo naa ba wọn wi nitori wọn lọra lati gba ohun ti Iwe Mimọ́ ti sọ nipa Kristi gbọ́. Ijọba Rẹ̀ ki i ṣe ti ayé yii, o si jẹ ọranyan fun Un lati kú ki O ba le gba araye là; ṣugbọn yoo tun jinde. A ti mu Iwe Mimọ́ yii ṣẹ, ṣugbọn òye wọn ṣokunkun sibẹ, bẹẹ ni wọn ko si mọ ọkunrin naa ti o n ba wọn rin lọ, ti O si n ṣe alaye Ọrọ naa.

Nigba ti wọn de ileto ti wọn n lọ, ti Oun si ṣe bi ẹni pe O n tẹ siwaju si i, awọn ọmọ-ẹyin rọ Jesu pe ki o ba wọn wọle lati jẹun. O gbà; nigba ti a si pese ounjẹ naa silẹ tan, O duro ni ipo Rẹ̀ gẹgẹ bi Olori, O si gbadura sori ounjẹ ti wọn fẹ jẹ. Nigba naa ni awọn ọmọ-ẹyin wa mọ pe Oluwa ni – O si nù mọ wọn loju.

**Ipada Si Jerusalẹmu**

Inu wọn dun pupọ pe wọn ri Jesu laaye lẹẹkan si i to bẹẹ ti wọn mu ọna wọn pọ̀n lẹsẹkẹsẹ pada lọ si Jerusalẹmu. O to irin ibusọ meje aabọ, ilẹ si ti ṣú, ẹsẹ̀ ni wọn o si rin lọ, ṣugbọn ko si ohun kan ti o le dá wọn duro. Wọn ti ri Jesu laaye!

Wọn de si yàra ti awọn Apọsteli pejọ si, ṣugbọn ki wọn to ni anfaani lati sọ ihin rere wọn a sọ fun wọn pe Peteru paapaa ti ri Jesu. Nigba ti wọn n fi ayọ nla sọ ti Iṣẹlẹ iyanu nla yii, Jesu fara hàn laaarin wọn. Ko ba wọn wí, bẹẹ ni ko tilẹ rán wọn leti pe wọn kọ Oun silẹ ninu ọgbà ni. Dipo eyi O sure wọn O si wi pe "Alafia fun nyin." Ko fẹ ki ẹru ba wọn, ṣugbọn ki wọn gba Oun gbọ́. O fi ọwọ́ ati ẹsẹ̀ Rẹ̀ hàn wọn, ati ihà ti ọmọ ogun Romu ti fi ọkọ gún. Wọn ko tun le ṣiyemeji mọ pe Jesu ni tabi Oun kọ́.

Ṣugbọn iru ara wo ni O ni? O ti kú, wọn si ro pe iwin ni. Ṣugbọn Jesu beere fun ounjẹ, O si joko O ba wọn jẹun. Ara ologo ni O ni eyi ti o le la ogiri kọja lọ; sibẹ ki i ṣe iwin (Luku 24:39).

**Ihinrere Fun Gbogbo Eniyan**

Fun ogoji ọjọ ni Jesu n fara hàn laaarin awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀, O n ki wọn laya, O si n fun wọn ni aṣẹ fun fifi idi Ijọ kalẹ. O fẹrẹ to akoko fun Un lati lọ si Ọrun, ki O si fi wọn silẹ lati waasu Ihinrere. O ṣeleri lati rán Olutunu ti yoo kọ́ wọn ni ohun ti wọn o sọ, ti yoo si fun wọn ni agbara nla ati igboya mimọ́ niwaju awọn ẹlẹṣẹ. Lati Jerusalẹmu ni wọn o ti bẹrẹ iṣẹ-iranṣẹ wọn, ṣugbọn wọn ni lati lọ waasu fun awọn orilẹ-ede iyoku bakan naa. Eyi jẹ ohun ti o ṣoro fun awọn ọmọ-ẹyin, paapaa fun Peteru lati moye rẹ̀. Wọn ro pe igbala jẹ ti awọn Ju nikan, ṣugbọn Jesu wi fun wọn pe gbogbo eniyan ni o le ri igbala bi wọn ba ronupiwada ti wọn si gba Ẹjẹ ti Oun ta silẹ gbọ́.

**AWỌN IBEERE**

1. Bawo ni a ṣe fi edidi di iboji naa? Bawo ni Jesu ṣe jade kuro ninu rẹ̀?
2. Ki ni awọn ọkunrin meji ti wọn n lọ si Emmausi n sọ?
3. Ki ni Alejo ni sọ fun wọn nipa Iwe-Mimọ́?
4. Nigba wo ni awọn ọkunrin meji naa mọ Alejo nì?
5. Ki ni ohun ti o ṣẹlẹ nigba ti wọn pada si Jerusalẹmu?
6. Awọn aṣẹ wo ni Jesu pa fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀?